“Ẹni ti o buru julọ ninu awọn eniyan ni ti ole jija, ni ẹni ti o n ja irun rẹ lole” o sọ pe: Bawo ni o ṣe maa ja irun rẹ lole? O sọ pe: “ Ko nii rukuu dáadáa, ko si nii ṣe iforikanlẹ rẹ laṣepe”

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ẹni ti o buru julọ ninu awọn eniyan ni ti ole jija, ni ẹni ti o n ja irun rẹ lole” o sọ pe: Bawo ni o ṣe maa ja irun rẹ lole? O sọ pe: “ Ko nii rukuu dáadáa, ko si nii ṣe iforikanlẹ rẹ laṣepe”.

[O ni alaafia] [Ibnu Hibbaan ni o gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe dajudaju ẹni ti o buru julọ ninu awọn eniyan ni ti iwa buruku nibi ole jija ni ẹni ti o maa n jale nibi irun rẹ; ìyẹn rí bẹ́ẹ̀ nitori pe ẹni ti o ba mu owo ẹlomiran, o ṣeeṣe ki o ṣe anfaani pẹlu rẹ ni aye, yatọ si ole yii, dajudaju oun ja ẹtọ ara rẹ lole ninu ẹsan ati laada, wọn sọ pe: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, bawo ni o maa ṣe jale ninu irun rẹ? O sọ pe: Ko nii ṣe rukuu rẹ laṣepe, ko si nii ṣe iforikanlẹ rẹ laṣepe; ìyẹn maa rí bẹ́ẹ̀ pẹlu pe ki o maa kanju nibi rukuu ati iforikanlẹ, ti ko nii mu mejeeji wa ni ona ti o pe.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/65100

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee